# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA
No. 718 SATURDAY JUNE 13, 1964 (2D

## Ẹni Ọwọ Kalẹ Fẹ Ya Duru Si Mimọ

IJẸBU ODE:- Lohin ko to afojuba ni Duru nla kan ti awọn Ijọ Ọlọrun "Emmanuel Church" Italupe Ijẹbu Ode ra fun Ile Ọlọrun awọn, eyiti nwọn fẹ ṣi ni oni ọjọ abamẹta ti iṣe ọjọ ketala oṣu yi ni Itapeju Ijẹbu Ode ni dede agogo mẹwa owurọ yi.



I. S. Kalẹ

Irohin fi ye wa pe, ẹgbarun ponun (£10, 000) ni awọn Ijọ Ọlọrun na ra Duru titun na ti nwọn fẹ yasimimọ ni owurọ yi. Ẹni ọwọ Biṣọbu Seth Kalẹ ya Duru simimọ ti iṣe Biṣọbu Eko ni yio si pẹlu iranlọwọ Biṣọbu Odutola ti iṣe Biṣọbu Agba fun agbegbe Ibadan.

A gbọ wipe, lati alẹ ana ni awọn eniа ṣarakisaraki ti nwọn ti fi iwe ipe ranṣẹ si ti nde sinu ilu na

Awọn ọjẹgbọn nipa iṣẹ Duru ti yio lu Duru na ni owurọ yi ni Ọgbẹni Fẹlẹ Ṣhowande ati Ọgbẹni Abiyọmi Phillips.

Oniwe Irohin wa Ejoogboro lọ si Ijẹbu Ode ni owurọ yi, yio si fun nyin ni ẹkunrẹrẹ irohin ati aworan Didun na ninu iwe wa ọsẹ ti mbọ yi.

# IJỌBA FẸ SAN ẸKUNWO OṢU FUN AWỌN OṢIṢẸ

ẸNUGUN:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbero fun Ogunlọgọ enia ti nwọn wa si ipade pajawiri ti awọn Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe ni Owurọ ana ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe, Dọkita Michael ti iṣe Alakoso Ijọba ipinlẹ Ila Orun Naijiria ṣe alaye fun gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na pe ki wọn o maṣe binu pe on pe wọn ni ojiji ati laiko sọ tẹlẹ.

Ohunti on pe wọn si ni ti awọn oṣiṣẹ ti nwọn da Iṣẹ silẹ ti nwọn ko ṣiṣẹ mọ, nitori ọran ẹkunwo owo oṣu, eyiti Igbimọ Morgan ṣe. pe ki Ijọba fi owo kun owo oṣu awọn oṣiṣẹ.

Dọkita Okpara ṣe alaye pe, Apapọ ijọba lo ṣe ileri fun awọn oṣiṣẹ nigba ti nwọn kọkọ da iṣẹ silẹ ninu Ọdun to kọja pe, awọn yio san ẹkunwo owo oṣu fun gbogbo awọn oṣiṣẹ, ṣugbọn ki awọn to le san owo na, awọn yio kọkọ yan Igbimọ Oluwadi kan lati wadi Ọran na wo na.

Bi Igbimọ na ba ṣe iwadi tan, iye ti o ba tọ to ti o si yẹ lati fi kun un fun awọn oṣiṣẹ awọn yio san owo na.

Ṣugbọn nigbati Ijọba yan Igbimọ na tan, ti Igbimọ na si wadi iye ti awọn oṣiṣẹ ngba, ti nwọn mọ iye owo ile ti wọn nsan fun owo ile, iye ti nwọn fi njẹun ki oṣu to pari, iye ti nwọn fi npamọ ati iye ọmọ on iyawo ti ẹnikọọkan wọn bi.

Lẹhinna ni Igbimọ na rii wipe iye ti awọn oṣiṣẹ ngba ti oṣu kan ko to wọn na ki oṣu to pari, o si paṣẹ pe ki Ijọba fi ponun mẹta mẹta kun owo oṣu awọn oṣiṣẹ, ki ẹniti ngba ponun mẹsan (£9) maa gba ponun mejila (£12).



Oloye J. M. Johnson

Lẹhinna, ki Ijọba si san owo ọya oṣu mẹsan fun awọn oṣiṣẹ, ki eyi bẹrẹ lati oṣu kẹwa ọdun ti o kọja titi di oṣu kẹfa ọdun yi.

Dokita Okpara ni Apapọ Ijọba kọ imọran Igbimọ Oluwadi na, o si tun kọ lati san owo ọya ati ẹkunwo oṣu fun awọn oṣiṣẹ.

Dokita Okpara ni on, gẹgẹbi Alakoso Ijọba faramọ pe, ki Ijọba san owo na fun awọn oṣiṣẹ.

Gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni nwọn faramọ imọran Dokita Okpara lati san ẹkunwo owo oṣu na fun awọn oṣiṣẹ gẹgẹbi ohun ti o tọ si wọn.

Irohin na tun ṣe alaye pe, Ijọba na ko fẹ ki o jẹ pe, Ijọba Ipinlẹ Ila Orun nikan lo san owo na ṣugbọn ti nwọn ba le ri Ijọba Ipinlẹ kan tabi meji ti o faramọ eto na. Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ti ṣetan lati san ẹkunwo owo oṣu fun awọn oṣiṣẹ nisisiyi, ki gbogbo wọn o si le pada si ẹnu iṣẹ wọn.

Lẹhinti ipade na pari, Ọgbẹni M. E. Ajuluchukwu, Ọga Agba Ile iṣẹ Minista Alamojuto eto irohin fi ye Oniwe Irohin wa pe, Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ti ṣetan lati san ẹkunwo owo oṣu ati owo-ọya fun awọn oṣiṣẹ bi Ijọba miran ni Naijiria ba le ṣikeji awọn ki o maṣe jẹ wipe awọn nikan ni awọn san owo na.



Oloye M. I. Okpara

## Ijọba Iwọ — Orun Rọ Adegbenro L'oye

IBADAN:- Ni deede agogo marun irọlẹ ana ni irohin kan wa lati Ile iṣẹ Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pe, Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti rọ Alhaji D. S. Adegbenro loye gẹgẹbi Balogun Ẹgba

Alhaji D.S. Adegbenro ni awọn Ẹgba ti fi jẹ oye Balogun, ẹniti o ba si jẹ oye Balogun yi ri o gbọdọ tun jẹ oye Ekẹrin Ẹgba.

A gbọ wipe, ninu ipade kan ti awọn Oloye Ija ye ni Abẹokuta laipẹ yi ni nwọn ti ṣe pinu pe, oye Ekẹrin ko tọ si Alhaji Adegbenro, nwọn si kọwe si Gomina Ipinlẹ na lati rọ Alhaji na loye.

Lẹhin eyi ni Ijọba ba fi ọwọ si iwe na pe ki nwọn yọ Alhaji Adegbenro ni oye ni ana. Ijọba si fi aṣẹ si iwe na.

## Ko Si Ipade Gbangba-Ode

IBADAN:— Ni agogo meji Ọsan ana ni Onirohin wa ni Ibadan fi ye wa pe, Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti pa a laṣẹ pe ko gbọdọ si iwọde tabi ipade gbangba Ode ni gbogbo awọn ilu ti o wa ni agbegbe Eko.

Ninu awọn ilu ti Ijọba sọ pe, ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe iwọde ninu wọn ni Ikorodu Badagry, Agege, Ikeja, Ajegunle, Awori, Isọlọ, Mushin, Shomolu, Ilupeju, Oshodi, Ajegunlẹ, Bariga.

Irohin na fi ye wa pe, ẹniti o ba tapa si Ofin na yio lọ san adọta ponun (£50) ni kotu tabi ki o lọ fi ẹwọn Oṣu mẹfa jura

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU (Apa 17)

**Lati Ọwọ J. O. Shoyinka**

Ibiti mo ba ọrọ mi de niyi Nwọn ko dahun iru wa bi Ẹbọra yi, o ni ẹnyin buruku yi, ẹnyin enia abirun-lori ṣe emi lẹ fi npe igi? Ohun ti o ṭẹ ṛyin ihin ẹ o sọ fun mi ki ngbọ Alẹ oni ni a o na a tan bi owo. Ọgo mi ni ngo fi ṣe nyin lọṣẹ, oku iṣẹju kan fun nyin, Ẹ sọrọ!

Ige da Ẹbọra yi lohun, o ni Ọlọrun to da Ẹbọra lo da enia Alejo lo wa nihin ki iṣe wipe afẹ mọọmọ di ẹ lọwọ ni, o yẹ ki ẹle sanu wa ninu iru ipo ti a wa yi Jọwọ maṣe fi ọgọ rẹ ki wa pa. Abẹ ọ, Iwọ Ẹbọra Anikanjẹ. Ẹbọra yi duro si i o nronu esi ti y o fun Ige ti mọ pe o fẹ ṣẹṣẹ, o paṣẹ fun awọn apurọ rẹ pe ki nwọn jẹki wọn yin Oluwa logo nipa kikọ orin si Oluwa.

Bi Ige ati awọn aburo rẹ ti bẹrẹ si kọrin iyin si Oluwe Ẹbọra yi ko seniseji o bẹ, lu igbẹ lo ba poora, nigbati ilẹ mọ nwọn bẹrẹ irin ajo wọn.

Lẹhin igbati nwọn ti jiyan lori ọna ti nwọn o gbe titi ti nwọn ko si fi ori rẹ ti si ibi kan, olukuluku wọn mu ọna rẹ pọn.

Kete ti Ogbojuleogun ati awọn aburo rẹ ya si ọna yi tan, ni wọn ngburo konkonma, Juju, Agidigbo. Sakara Iya ilu, Aro, Ṣẹkẹrẹ dapomọ dundun, fere ndun tantantan, titi ibẹmọ lọ kadara ko si kori ko tabi, epo kan nibẹ, o ndan bi kolọjia Ogbojulegun ba iṣẹ rẹ pade nitoripe ninu ile apejẹ yi awọn obinrin kun ibẹ. Oniruru ni wọn omiran ẹwẹ si dudu, awọn "eji wura" si wa nibẹ sua. Olukuluku wọn bẹrẹ si jo omiran njo konkoma omiran njo "kusimilaya" Ọpọlọpọ lo njo "Idi nlanla", Nigbati Ogbojuleogun foju kan abọdi nlanla, o bẹrẹ si jo pẹlu wọn gẹgẹbi ẹti mọ pe o fẹran obinrin. O ti gbagbe ohan ti o le e de ibẹ, awọn aburo rẹ ko roju rẹ nilẹ mọ, o ti mu ọti yo gbari, o nta gbọngbọn sẹhin sọhun

Nigi ati Ogbojuleogun yo tan, o gbagbe iṣẹ, Obinrin agbere kan tan an lọ sinu iyẹwu rẹ ki o lọ tẹ ifẹkufẹ ara rẹ lọrun Obinrin yi ti ja owo ara rẹ o tubọ fun ni ọti lile mu o ti sita

Ogbojuleogun ko mọ ọna mọ o bẹrẹ si rin kiri bi agutan ti ko loluṣọ.

O to nkan bi agogo mẹjọ owurọ. ko to mọ ọna ile ọdọ awọn ẹgbọn rẹ, Ogbojuleogun gbọnra mu gbu u, ko si kọbọ ni apo rẹ mọ, o nronu bi on yio tise ri owo na lọna irin ajo wọn. Sugbọn awọn ẹgbọn rẹ ni ki o ma mikan, lẹhin igba ti nwọn ti bu u tan fun iwa aisedede rẹ

Iya ti o wa nihin ko ṣe e fi ẹnu sọ nitoripe ẹnikẹni ti o ba ti jẹ ọdẹ ko le kọja ninu ilu yi, Ilu Olu-Igbo yi. kun fun oriṣiriṣi ẹranko ti o nfi ẹsẹ rin ati awọn ti o nfi aiyawọ.

Ariya ọjọ na ko ṣe e fẹnu sọ, nitoripe Kiniun Ọba awọn ẹranko to se alaga. Erin lo ṣe igbakeji rẹ awọn Ọgbẹni bi Imado, Turuku Ẹlẹdẹ Egbin. Igala Agbamurere ati a w ọ n ẹranko miran ti ako le daruko tan lo ṣe isọna gbe wọn lọjọ na Elegbede ni o nlu iya ilu, ọbọ nsan ọmọle, awoko lo nkọ orin. Inu Ọba dun to bẹ gẹ ẹ. o ni ẹniti oba le jo daradara ju, ni on o fi jẹ arole on.

Kini awọn ọmọ Onilogbo gbọ bayi si, nwọn mu ijo jo, okiki nta ge e, bi enia ti njo bẹni awọn ẹranko njo pẹlu, gẹgẹbi ẹnyin paapa ti mọ iṣesi ọbọ. ko kere ninu ijo rara, ojo t i t i o bẹrẹsi gbe okiti sugbọn ko si bi a ti leṣe ẹranko to ko hu-



ọgbeni J. O. Shoyinka

wa enia, odiodi la ngbẹsẹ ko ba i l u mu, ni kukuru Ogbojuleogun ni o jo dara julọ.

Olu igbo fi Ogbojuleogun ṣe arole rẹ. Nigbati odi ọjọ keje Olu igbo paṣẹ fun Alagba ilu pe ki o kede ni irọlẹ oni on fẹ gbogbo awọn ara ilu patapata, atọmọde atagba, ati oyun inu pẹlu, nitoripe on ti y a n arole on, on si fẹ fi han wọn, olu agogo yi ilu ka gẹgẹbi aṣẹ Olu igbo.

Nigbati odi irọlẹ E r i n fọn gbogbo awọn ẹgbẹ rẹ darijọ si ibi kan, Ẹfọn ṣe bakanna gbogbo wọn tun d a r i j ọ si ibikan, Kiniun Ẹkun, Amọtẹkun Ikoko parawọn pọ sọkan Igaala Egbin, Ẹ t a, Agbanrere, Ekulu ati awọn ẹranko miran tun fi ara wọn ṣọkan bẹ ẹ.

Gbogbo Ejo inu igbo pejọ si ọdọ Ejola, awọn bi Okete, Ẹku, Ọya, Ehoro, wa lẹgbẹ kan, awọn Ọgbẹni bi Igbin. I j a p a ati Ọpun duro sẹgbẹ kan.

Awọn ẹranko bẹrẹ si towo rin. O di ile Olu igbo Kiniun ọba awọn ẹranko lo siwaju, Ẹkun tẹle e awọn ẹranko yoku wa tọwọ lẹhin rẹ Nigbati Ogbojuleogun ri wọn lokere ti nwọn mbọ, nṣe lo dimọ Olu-Igbo nitoripe ẹru mba a, ki awọn ẹran wọnyi ma ba a pa on jẹ awọn ẹgbọn rẹ ti sapamọ

Wo Oju Ewe Karun

# Igbẹhin Lọran

Lati ọwọ AFỌLABI ỌLABINTAN

Bọlaji ohun se wa ko kere,
Ọmọ oyila gbogbo oju lo nw'ẹiyẹ
Nwọn ditẹ ditẹ kilẹ gboloore mi
Nwọn dalẹ titi kodo gboloore lọ
Ṣugbọn otitọ inu ju madarikan
Ododo 'nu ju ogun nla lọ
Bi nba ni nsohun ti nbọ
Ki ntilẹ gbagbe eyi to ti lọ
Adiẹ a h'ehin, akololo a pe baba
Ṣugbọn ọrun ma a nwo, Mọbọlaji
kii sọrun ẹnikansoso
Bile Ọba wo gbogbo ori ade la ba a lọ
Mo dele alara oni ko si nkan
Mo dele alagbo, o ni ko sewu
Mo lomi nkun o nbori arafa
Iyan nu titi iyan dohun jijẹ
Bewu yio ba si laiye nkọ ?
Ṣọ digba gbogbo wa ba dẹwọn irin
Bọlaji nwọn gbe ọrun alẹ
Nwọn npe gbogbo ọmọ owo
Nwọn lọ'runmila lolu ofin
Mo l'odi kọtadinlogun lo yọ ni
Tabi igba wo l'ọrunmila dọofin
To fẹ ko gbogbo wa sin
Lagbaja ni ka feyedenu lo tọ
O lohun a fotẹ mu titẹ ni itẹ ni
Ẹni badalẹ ni a balẹ lọ
Okete to dafa lo nderan lọwọ ọdẹ
Ekolo ti ko juba lẹ a da fẹmọiẹ
Gbogbo ẹni ibi nii ba bi wọlọ
A a l'ohun nse wa
Nwọn ni kaka ka foribalẹ f'Adenle
Ka ba komberi to ni tawọn
Kaka ka dọbalẹ f'Alabi agba
Kara Derele Ajayi lowọ
Ka ba uku-uku laiye lo dara
orin:-Ṣubgọn igbẹhin lọran
Bo ndun loni igbẹhin lọran
Igbẹhin o igbẹhin lọran.

# IWE SI OLOTU

## Ilora Yio Wa Labẹ Awẹ Bi ?

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ ọloyin mọmọ ti o nkọwa ni ọgbọn ati oye ki fi ẹdun ọkan mi han awọn onkawe Irohin Imọlẹ jakejado ile Naijiria lori ọrọ na ti o jade ninu iwe nyin ti ọjọ kọkandinlogbọn osu kẹrin ninu ọdun yi pe. ilu Awẹ yio daduro ati awọn ile to wa labẹ re bi. Fiditi Ilọra, Jobele.

Ọrọ na ru, ẹ ọju, kosi ti ye mi rara ni, iwe itan sọ fun wa wipe Ilora ni awọn kọkọ tẹdo sisaju awọn to wa ni Ọyọ ati agbegbe nigbati Ọlọrun si ran wa awọn ti o bọ Ajaga Isingba Ọyọ ile to watun jọ pe Awẹ ni a o tun mọ sin.

Ṣugbọn bi ẹnyin alagba ba ri wipe o dara bẹ ko buru o.

Olotu ọkọ ọba ko sa yin lẹsẹ o

Emi ni,

E. O. Kẹhinde

ILỌRA



Ọgbẹni Julius Ọdẹku

Ki ba dara, ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ba ku jẹ ki awọn ilu to ti yio parapọ se Ijọba Ibilẹ kansoṣo ba ni Ijọba Ibilẹ ti wọn lọtọọtọ mo le wipe ki ba dara gan ni.

Nitoripe, ilu Ilọra ko kere larin awọn ilu to wa ni agbegbe Ọyọ Ireje to jẹ lojo temi, nitorina mo fẹ ki ẹ jẹ ki a tun ọrọ na yẹwo daada.

## Ẹ La Eyi Yemi

Ẹjọwọ, ẹgba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti nkọwa ni ọgbọn ati oye bere ọrọ to nru mi loju lọdọ awọn ọjọgbọn ati Oloye ti nka iwe nyin ni oju mejeji ki nwọn kele fi ọrọ na ye mi daada.

Mo fẹ ki awọn to mọ mimọ ninu ọrọ mimọ Ọlọrun to njẹ Bibeli ki nwọn loye nitoripe a to mefa ti a nfa ọrọ na mọ ara wa lẹnu titi ti ko si ri oju ọtun, ni mo ba sọ fun wọn pe ti a ba ẹ kọ ọrọ na sinu iwe Irohin Imọlẹ ki nwọn la ọrọ na ye wa yekeyeke.

Nje otitọ ni pe Maria Iya Jesu tun bi ọmọ miran lẹhin Jesu To ba jẹ bẹ, mo fẹ mọ orukọ awọn ọmọ na.

Inu mi yio dun pupọ ti awọn onkawe Irohin ba le la ọrọ na ye mi daada pẹlu ẹri ninu Bibeli

Abọ mi re Olotu, Ọlọrun ko jẹ ki o rẹ nyin o, Oluwa yio mọ ran nyin lọwọ aṣẹ.

Emi ni,

J. A. Enijala

ESIẸ

## Ẹ Ma Ka Irohin Imọlẹ Lojojumọ

## Hadja Limọta Sinku Baba Rẹ

ILARO:- Hadja Limọta Adeshina Onisowo pataki ilẹ Naijiria ti apele orukọ rẹ njẹ Hadja Limọta yaayi Ilaro Ẹlẹyinju Ẹgẹ fọmọyọ nigbati Alhadji Adeshina, baba rẹ fi ile ṣe sa ọ bora lẹnu lọlọyi.

Lati ọjọ ti baba oninure na ti ku titi bi mo ti nkọ irohin yi ni Hadja Limọta Adeshina ti ngnawo bi ẹlẹda. O na owo, o si nse o nsọ

Ẹnu kọ irohin ni ibi aṣeyẹ sinku na ni ilu Ilaro. Ni aisun ọjọ mẹta oku na, ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkandinlogbọn oṣu ti o kọja yi, Hadja Limọta dabira gbogbo adugbo te dabi ọsan.

O na wabiwọsi owo fun ọkẹaimọye enia ti o ti igun mẹrẹrin ilu Naijiria wa si ibi aṣeyẹ oku na.

Ẹsẹ awọn Alhadji pe, ẹsẹ awọn Alhadja pe, ẹsẹ awọn alufa pe, ẹsẹ awọn ọlọla ati borokinni si pe sọsọ sibẹ. Alhadji Y. A. Disu pẹlu awọn Alhadji gbajumọ ti o wa lati Eko lẹjọ ọjọ mẹjọ oku na.

Ki Ọlọrun kẹ oku na, ki O si fi awọn ọmọ rẹ gbehin Hadja Limọta Yaayi Ẹlẹyinju Ẹgẹ Adesina Amin o.


## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a npe ni

'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajebidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹrakù tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko Lẹhin ti o ba lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ehin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu ibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn ti nodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.

BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

# Nwọn Bere Lọwọ Akintọla Idi Rẹ Ti O Fi Yọ Ọni

IBADAN:- Awọn ẹgbẹ ọdọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria (Western Nigeria Youth Front) ti kesi Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye S. L Akintọla ki o ṣe alaye idi rẹ ti o fi yọ ọba Adesọji Aderẹmi, Ọni ti Ifẹ gẹgẹbi Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun.

Eyi si de ọwọ wa lati Ibadan ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kinni oṣu nigbati awọn ẹgbẹ ọdọ na nbere idi rẹ ti awọn Ọba mejila kan lati Ipinlẹ Iwọ Orun fi nsọ fun Olotu Ipinlẹ Ila Orun ati olori ẹgbẹ Alakukọ pe ki o ma ṣe rin irin ajo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ninu iwe ti awọn ẹgbẹ ọdọ na ke si awọn Ọba na pe eleyi jẹ ohun elebu lati gbọ ati pe kini ṣe ti nwọn kuna lati bere lọwọ Oloye Akintọla nigbati o yọ Ọba bi Ọni ti Ifẹ gẹgẹbi Gomina enia dudu ekinni ni Ipinlẹ na ?

Awọn ẹgbẹ ọdọ na ṣi sọ pe eleyi jẹ iwa to buru ati alaini igbẹkẹle lati ma r i pe awọn Ọba to jẹ Baba fun wa ma nda si ọrọ ija oṣelu to bẹ silẹ larin awọn ọmọ wọn.

Awọn ọdọ na si tun sọ ninu iwe wọn pe gẹgẹbi Baba pe nwọn kuna lati sọ fun aiye gbọ pe nwọn jẹ olododo Baba ti ko ni gbe ọkan ọrọ oselu ti awọn ọmọ wọn lati jẹ ọlọtọ ati olododo.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na si ti fi ẹda iwe na ranṣẹ si Arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dọkita Nnamidi Azikwe, Olotu Ijọba apapọ Ọlọla Abubakar awọn Olotu Ipinlẹ kọkan ni Naijiria ati Oloye Fani-Kayọde igbakeji Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni R. O. Ọlatunji Akọwe agba ẹgbẹ Hebert Macaulay Dẹmọ Youth Brigade si ti bu ẹnu ẹtẹ lu awọn ọrọ ti ẹgbẹ Okpara Youth Brigade ati ti Ọgbẹni S. B. Okoro ti o jẹ, akọwe agba ti ẹgbẹ Herbert Macaulay Youth Brigade ti Ipinlẹ Iwọ Orun nipa ọrọ ti irin ajo ti Olotu Ipinlẹ Ila Orun Dọkita Michael Okpara yio ṣe si Ipinlẹ Iwọ Orun Ọgbẹni Ọlatunji si ṣe apejuwe ọrọ na gẹgẹ i alaitọna ati alairisọ.

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 - Feb18) Iṣẹ pọ fun ọ lati ṣe,ero rere ni yio sọ si ọ lọkan. Iṣẹ kan ti o nṣe tabi ọna ti o na owo nfẹ atunṣe.

PISCES (Feb19–May20) Ọjọ oni jẹ ti aanu fun iṣẹ ati fun ara ẹni pẹlu ṣugbọn mase fi ọkan ara rẹ wewu nipa ede koyede lati okere wa, ṣe atunse miran.

ARIES (May21-April19) Gbidanwọ, ki osi se ohun ti o ngba alagbara kan pade ti yio ṣe atilẹhin fun ọ

TAURUS (April 20-May20) Owurọ ọjọ oni lo dara fun ọ ju bi o ba di ọ ọ rọ amọdi fẹẹrẹ kan yio ṣe ọ ọrọ nipa owo yio de fuuọ lọ se itọju ara re.

GEMINI (May21-June 20) Ọrọ pataki kan mbẹ nilẹ ti o nfẹ iyanju bi bẹ kọ yio da ijọngbọn nla silẹ ti ọwọ rẹ ko ni ka bi o ti wu ki o ri ire ko jina si ọ.

CANER (June21–July20) Maṣe tun se atunṣe mọdaru nipa ọrọ kan ti o ti npa ri lọ dẹdiẹ bẹni ki o ma se tun da ọrọ owo sisan miran silẹ ọrọ ẹbi ati ọrẹ yio ma goke siwaju

LEO July21-Aug22 Ẹnikan ti iwọ nferan yio ma jowu rẹ ni biba ọja tali yan ọ lodi ọrọ ija kan yio ṣẹlẹ sọ ti yio da ijọngbọn kan silẹ larin awọn ẹbi tabi ọrẹ rẹ

VIRGO (Aug 23-Sebt 21) O to akoko ti oni lati ṣe ipinnu nipa ọrọ ara rẹ kan ti ẹti mbẹ nilẹ, ohun kan ti osi nro l'ọkan rẹ, yio mu ire wa.

LIBRA (Sept 23- Oct 23) Ọkan re yio daru di nipa ọrọ kekere kan ti o ti wa nilẹ. Ṣugbọn ede ko-yede kan nfẹ bẹ silẹ larin iwọ ati ọga, yio si kuro laipẹ tunbọ ṣe suru, ire ni igbẹhin rẹ yio jasi.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Akoko to ti ẹ ni lati pariariyanjiyan kan ti o ti wa nilẹ, arisiki yio gbe rẹ ga.

SAGITHARIUS (Nov 23 Dec 21) Ọjọ ire ni oni jẹ ati iranlọwọ ẹda, fi ọkan balẹ pe iṣẹ rẹ ma lọ geregere, ohun ayọ kan yio ṣẹlẹ larin iwọ ati olufẹ, inu rẹ yio dun ara rẹ yio si ya.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Irin ajo yio jẹki o riṣẹ ṣe, iwọ yio si ri ere nla jẹ ninu gbogbo ohun ti o ba dawọ le, ifẹ yio gbilẹ larin iwọ ati iyawo rẹ, kọ iwe si awọn olufẹ rẹ.

# Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹrinla oṣu yi (14/6/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Lagos.

Ao si tun ti tẹyọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ ki ẹsi tete de.

LATEEF BAB LOLA
Akọwe Agba


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TONIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Toniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣiṣẹṣẹ ti o kọ le jeun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja Ọgbọn odun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ s'i dan pada. Ara re yio ma gbe kankan nigbakugbɑ y'Arẹ" nigbakugba yio salọ Pẹlu, Igba-dun ati alafia diro de ọ. Iyẹn daju. BereEgbogi na ni Ṣọbu:a

ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street, Yaba
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone 2287 Nigeria (Ọja Ita Faji Lagos)
NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 718 SATURDAY, JUNE 13, 1964 (2D)


## Ọlọṣa Fọ Ṣọbu Alhaji Yaya

Idaamu nla gbogbo enia ti nwọn a ni adugbo nigbeti awọn Fọle-fọle ọlọṣa kan gbe mọto kia-kia bọọsi kan, No. L C 4032 wa ni ẹnu ọna ṣọọbu Alhaji Yaya ti o nla agogo ni nọmba 22 Dosumu St. Eko ti ko gbogbo ọja ti ole ni ọkẹ mẹrin (£80,000) ninu ṣọbu na lọ ni ọjọ Ọ ọ 'i u ti iṣe ọjọ kẹwa osu yi.

Ọgbeni Aroworọwọn ti ọrọ na ṣoju rẹ ṣe alaye fun onirohin wa Ejongboro pe, ni dede agogo mẹrin ọjọ na ni awọn ọlọṣa na gbe mọto kia-kia kan de, ti nwọn si fi ipa ṣi ilẹkun na wọle.

Baba ti o ṣiṣẹ alẹ ni ṣọbu na ṣi o fẹ lọ awọn ole na nwọn ṣe ni eṣe awọn ole na si ko ẹru inu ṣọbu na lọ ṣugbọn bi awọn aladugbo ṣe taji nwọn kole jade ntoripe awọn ọlọṣa na nṣọ akufo igo si gbogbo enia.

Ko pẹ lẹhin eyi ni awọn ọlọpa ti nwọn nkiri loru de, awọn ọlọṣa na si sọ awọn ọlọpa na ni igo nwọn ba sare ko ẹru na sinu mọto nwọn salọ ṣugbọn awọn ọlọpa fi mọto wọn le awọn ọlọṣa na de Abule-Ọja nibẹ ni nwọn ti ri ẹru na gba pada.

Alhaji Yaya kọ lati ṣe alaye ọrọ na fun Ejongboro lana nigbati awọn ọlọpa fi ọkọ wọn No NPF 825 ko ẹru na wa fun Alhaji Yaya, iya agba kan sọ fun Ejongboro pe, mọto onimọto ni awọn ọlọṣa na gbe ni arin ọde ti nwọn nwa ko ẹru ọlẹru.

Awọn ọlọpa nwa awọn ole na bi wọn ba ti ri wọn, ọọ ma gbọ.

# IJỌBA PADANU OGOJI ỌKẸ PỌNUN (£800, 000) !

PỌTA:— Gbogbo enia lo dorikodo bi ewe ọgẹdẹ nigbati Ọgbẹni Wednesday Uruakpa, ti iṣe Ọga Agba Ile iṣẹ awọn Alaṣẹ ọkọ oju omi (Nigerian Ports Authority nsọ fun awọn oniwe irohin pe, Ile iṣẹ on ti padanu owo ti o ju ogoji ọkẹ pọnun £800,000) lọ lẹnu igbati awọn oṣiṣẹ ti binu da iṣẹ silẹ yi.

Ọgbẹni Uruakpa tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ fun awọn oniwe irohin pe, gbogbo awọn ọkọ oju omi ti nwọn ko ẹru wa lati ilu Oyinbo ni gbogbo wọn wa ni eti Ebute Pọta ti ko si si awọn oṣiṣẹ ti nwọn o ja awọn ẹru na silẹ ninu ọkọ.

O tun ṣe alaye pẹlu pe, bi awọn ẹru na ba tuu pẹ ninu ọkọ oju omi ju bayi ọ, awọn Oyinbo onişowo ti nwọn ni ẹru na tun le pe Ijọba lẹjọ pe Ijọba kuna lati gbe ẹru fun awọn lasiko, ko si ba ohunti awọn fẹ lo awọn ẹru na fun mọ.

Ọgbẹni Uruakpa tun sọ siwaju pe, gbogbo iṣẹ lo duro ṣiṣidi ni Ebute ti awọn oşişẹ joko kalẹ lasan ti nwọn ko ṣiṣẹ.

O wa pari Ọrọ rẹ pe, 'Iye owo ti Ijọba padanu rẹ titi di ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kọkanla Oşu yi ni a sọ yi, a ko si ti mọ iye ti owo na yio jẹ ki awọn Oşişẹ to le pada si ẹnu iṣẹ wọn.

"Şugbọn ni ojojumọ la ngbọ ninu ẹrọ-asọrọmagbesi pe, awọn Oşişẹ ti bẹrẹ iṣẹ wọn papa.

O wa pari Ọrọ na bayi pe, ' Ni ibi iṣẹ temi ni Pọta nihin yi, Oşişẹ kan ko ti pada si ẹnu iṣẹ o."

Oniwe irohin wa ti o lọ si Ile iṣẹ awọn Alaşẹ Ọkọ Oju omi Eko (N. P. A.) lana fi ye wa pe, awọn Ọga Agba Ọkọ oju Omi na ko ti ṣe iṣiro iye owo ti awọn ti padanu, ṣugbọn owo na yio ju ti Pọta lọ.

Nigbati Oniwe irohin wa Ejongboro de Apapa lẹsan ana, o fi ye wa pe, Ọkẹ meji o le Ọgọrin (40,4000) ni apo ẹpa, ekuro ati koko lo wa ni Ebute ọkọ Apapa ti ko si ẹniti yio ko wọn ni Ebute.

Irohin fi ye wa pe, ni Ọjọ kẹwa Oşu yi ni awọn ẹru na fẹ lọ si ilu Oyinbo şugbọn ti nwọn ko ti lọ nitori awọn Oşişẹ ti nwọn da iṣẹ silẹ.

Ninu awọn ọkọ oju omi ti o nlọ si ilu Oyinbo ti awọn ko ti le lọ ni wọnyi:

Akasa Palm, Katsina-Palm, Makurdi Palm, Bonta Palm, Falkenger. Nester Manland, Sapele Palm, ati Aquileia.

Gbogbo awọn ọkọ wọnyi ni nwọn si gbọdọ ko ekuro ẹgbẹta (600) apo koko irinwo (400) apo kere- owu igba (200) ati apo ẹpa ẹgbaa (2,000) şugbọn gbogbo awọn ọkọ oju omi ati awọn ẹru wọnyi lo wa ni Apapa nisisiyi, ti nwọn ko si le lọ ibikankan.

Awọn oşişẹ lọ si ibi iṣẹ şugbọn nwọn ko şişẹ, awọn ọlọpa duro lẹnu ọna ile iṣẹ wọn, awọn oşişẹ nwo ọlọpa awọn ọlọpa na nwo awọn oşişẹ.


AWỌN EGBOGI ATAMATASE PATAKI TI ODAJU LATI ILU JAMANI FUN ITỌJU AKUN ARA ATI OJU-DIDUN PẸLU BERE EGBOGI:-

## SEDO – PAYAL

IPARA BI ORI

Jẹ ojulowo egbogi lati fi şẹ iwosan orişirişi arun awọn "ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi lo de ara gẹgẹbi ọwọ ẹsẹ tabi ara hihun tabi yiduo nigbakugba Inrun tabi akọ Inọrun, Ewo, Rorẹ kakiri oju, Ela, lapalapa. Ara sisu. Alefo, Ekusa lori ọmọde tabi agbalagba, ẹgbo ẹsẹ tabi Adaajinọ egbeẹsẹ ati orişirişi awọn amidi tabi awọn arun ara omiran gbogbo BENỌSINI EGBOGI

FURUNCULIN SIN-MINIU-TABLETS

Dara pupọ julọ fun awọn ti amodi ti a darukọ wọn si oke iwe yi ba nyọ lẹnu nitoripe iṣẹ rẹ ni lati ma ta gbogbo awọn "kokoro" buruku gbogbo ti o ta wa ninu "IJE ARA" enia, san patapata asi wa şẹ işẹ ribiribi ninu "oju" enia pẹlu. Awọn ti oju wọn a nia "su" tabi wo baibai tabi ti wọn ko le riran daradara lati ọna jinijini tabi ti o dabi ẹnipe nkankan wa afara si oju wọn yio bẹrẹ si riran Kedere.

Bi o ba ti le gbiyanju lati wa lo egbogi Jaisannu yi dede fun igba diẹ alafia yio de si ọ ju gbogbo rẹ lọ egbogi Furinmeulain yi atnn ma mu igbọuşẹ wọrọ wọrọ wa fun awọn ti inu wọn bale tabi ti wọn ki rigbonşẹ dede lojojumọ tabi ti igbonşẹ wọn mn nle kokoro nipa bayi jẹdijẹdi a bẹrẹ si ma yọ wọn lẹnu bẹni o si dara fun lilo awọn onijẹdijẹdi pẹlu Awọn egbogi meji yi yatọ si gbogbo awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri Şọqu ilu Eko ati igberikọ Bae wọn ri Şọbu anyin.

Waterloo (P A. T. ) Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Itafaji Lagos

Adedun Chemist 4 WakewaStree Yaba.
Işọlodumare Dispersory Oke-Bọla Ibadan.



## E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ si maa Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbgose Street Lagos Phone:- 21985
Editor:- TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street, Lagos (13/6/64)